# Ọba Adele fẹ ki Eko pada si Ipinlẹ Iwọ-Orun

*Lati oja ewe kini* Musulumi Eko.

Ninu ọrọ rẹ o fi han gbangba pe awọn fi gbogbo ara mọ ọ pe ki ilu Eko pada si Ipinlẹ Iwọ-Orun ati pe awọn ko fẹ nkan miran nipa eto Eko ju eyi lo. O si fi han pe Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o to gbe okan le fun idagbasoke ilu Eko.

Imam agba na, baba Mojisola wa yiju si gbogbo awọn enia ti o pe sibẹ, o si bere lọwọ wọn bi nwọn ba fẹ ki eto iṣelu Eko pada si arin awọn ilu Yoruba ni Ipinlẹ Iwọ-Orun ni tabi ki o wa ni gedegbe ni? Gbogbo wọn si panupọ kigbe li ohun rara lẹṣẹ kanna pe "a ko fẹ nkankan fun Eko ninu eto iṣelu ju wipe ki o wa pẹlu awọn ọmọ iya rẹ, awọn ilu ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun lo!"

O tun yi si awọn ijoye ati awọn ọmọ-Ọba ati awọn ibiga ati Ọba paapa fun ibere kanna. Gbogbo wọn si dahun bakanna. Oba na ṣe alaye pe on ko fi igbakan ni ọwọ ninu awọn Ẹgbẹ Oṣelu Titun "The Lagos "Separate State Movement" ti o nfẹ ki Eko wa gedegbe, ati wipe ohun ti awọn ijoye ati ara ilu on ba fẹ ni on fi ara mọ patapata porongodo.

Ọgọrọ awọn enia pataki-pataki ti o pe sibẹ si rọ Ọlọla Oloye S. L. Akintola, Gbakeji Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre, Aṣipa Ogbomoṣo ati Ọgagun awọn Ẹgbẹ Alatako ninu Apapọ Igbimọ-ola Aṣofin Ijọba Naijiria pe ki o sọ sinu ọrọ na. O si gba lati ṣe bẹ ẹ pẹlu iyọnda Ọba na.

Oloye Akintola ni ilu Yoruba ni ilu Eko nṣe lati iṣẹdalẹ wa. Nitorina o gbọdọ pada si ọdọ awọn ọmọ iya rẹ ni fun eto, eto ati irọrun. O ṣe ibere lọwọ awọn oludasilẹ ẹgbẹ gedegbe l'Eko wa ("The Lagos Separate State Movement) awọn olotu Ẹgbẹ na bi ọmọ-Oba Adelumola Ibikunle Akitoye, Ogbeni H. M. Alli-Balogun ati Lọya K. K. Kotun pe o da wọn loju pe Ikorodu, Epe, Ikeja ati Badagry yio pẹlu wọn ninu idasilẹ wọn yi? Nwọn pa pẹrẹjẹ. "Kẹkẹ p'ohun mawoko lẹnu nwọn ngwo pako bi malu ti o fi oju kan obẹ. T. O. S. Benson parẹ nibẹ nigbati nwọn nṣe ibere na ni. O ba f'oju kan S.L.A." O ba tiwi. ?"

Gbogbo ero ti o pe sibẹ bẹrẹsi yombo olohunyo, Oloye na pe "S.L.A! S.L.A.!! S.L.A.!!!. Ninu ọrọ Oloye na o fi han bi Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti ja Ọba Adele Keji kulẹ ninu Igbimọ Ibilẹ Eko "Lagos Town Council" ti nwọn fi dibo fun Dokita Abu Bakare Ibiyinka Ọlọrun-Nimbẹ ti nwọn fi ṣe Meyọ Eko dipo ki nwọn yan Oba na si aye na laini ibo ninu.

O si sọ iru aye nla ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre gbe Ọba na de l'oni ti o di Alakoso Igbimọ Ibilẹ Eko na. O ni awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre wa lati ṣe ire si gbogbo ilu karọ-oojire ni ati pe awọn si wa lati tubọ gbe Ọba Adele ga ni. Ninu ipari ọrọ lakaye rẹ o ni ki Ọba Eko ati awọn Ijoye rẹ ati awọn ara Eko ni igbẹkele si Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) fun idagbasoke ilu Eko.


K.B.S.

YARO

(REGD)

Awogba fun Ọmọde




ABIYAMỌ ETI RẸ MELO?

Asiko ojo ati otutu ti de nisisiyi:—
E ma jafara lati ni igo Egbogi "YARO" nitori fun ọtutu ABURADI, IKỌ-IGBONA - IGBAKU-GBA, tabi IDAGIRI awọn ọmọde ti nma yọju ni asiko ilẹ tutu yi—pataki fun awọn ọmọ ọwọ ti wọn ṣẹṣẹ fẹ bẹrẹ si hu ehin. IJAFARA - NI-IJA-ẸKUN. Egbogi bi "YARO" ko pe meji ni gbogbo ilu Nigeria ABIYAMỌ! ki iwọ ki o ripe oruko "YARO" ni o wa lara egbogi igo na. Ẹ o ri ra ni gbogbo awọn ti ta oja egbogi oyinbo.






'ANTEPAR' YIO LE GBO-GBO ARUN-MUJẸ-MUJẸ INU RẸ JADE LOOJỌ!

- 'Antepar' le yara le arun-mujẹ-mujẹ kuro ninu
- 'Antepar' ko l'ewu, bi o tilẹwu ki ọmọ kere to
- 'Antepar' dun l'ẹnu
- 'Antepar' ki i ba ni i ja nino

Mimu rẹ lẹẹkan yio le gbogbo aran mujẹ-mujẹ rẹ jade l'oganjọ!



'ANTEPAR'

ELIXIR

THE MARK OF BURROUGHS WELLCOME & CO.

Awọn Aṣoju wa ni Iwọ-Oorun Afrika ni i



Ẹ MA A POLOWO ỌJA NYIN SINU IWE Irohin Yoruba



"SIGA PIRATE NI MO GBADUN JU"




PIRATE

Siga ti o dara pupọ ni



Ohun mimu ti ẹnikẹni gbadun




oladun

KLIM

MILK

Gbogbo awọn ẹbi ni o ngbadun wara Klim, ohun mimu ti o ṣe ọ ni anfani to pọ bayi! Wara funra ara rẹ onjẹ to pe ni. Klim si dara, wara gidi ti omi rẹ ko pọju, sa fi omi si i gẹgẹ bi o ti wa ninu apejuwe ki o le di wara tutu ti o mun ẹrẹ, to mọkan tutu, ti o dara fun mimu ati fifi - pe onjẹ - pelu.

KLIM ni adun bakanna gẹgẹ bi WARA tutu ti ni.

## Ẹ MAṢE SE AIYA NYIN LE

Lati Ọwọ
AJANGOLOTO

# Eko Lainile-Lainara, Gedegbe? Rara

B'ILE le daboro k'o daboro patapata,
B'ilu le baje k'o baje balumo;
B'omo d'eru, b'eru d'omo ko kan wa,
T'ara wa lo ju, ire tiwa l'awa nwa kiri;
O difa fun Egbe Alakuko ti nf'ola Eko ta tete,
Ani, awon ti nfe ki "Diayin" d'alaṣe ile Oduduwa:
Awon irunbikunle, awon akotileta, arungun dede,
Nwon pimopo pelu Azikiwe,
Nwon fi irira won fun Awolowo ya Eko si "gedegbe",
Nwon so awon eni-ola-awon omo Eko d'ojiya:
Gedegbe; Ohanran d'alaṣe Igbimo ilu Eko,
Oba Eko d'eni "waawa" nfojudi
Awon ijoye d'odi, ninu oran ilu, nwon ko gbodo soro;
Ope Edumare, ope Ado onile, ope Egbe Afenifere,
Azikiwe iba ti d'alaṣe Iga Idunganran,
Ojike iba ti di Bajulaiye tabi Oloto;
Lori gbogbo iwosi at'abuku, omo Eko ko ronu,
Nwon ko bikita fun ogun ibi won,
Sibe, nwon nkigbe, "gedegbe l'Eko wa".
Nwon ti gbagbe pe eni so ile nu so apo iya ko,
Eni so oko nu k'apo ebi.
Ko ye ki Eko kuro lara Ipinle Iwo-Orun:
Nwon tele awon "tiwa l'a nwa", nwon gbe Eko ta,
Nwon 'tori ipo, nwon so Ite-oba d'apoti itiṣe Ibo;
Nwon ke, bi awon Ju ti ke nijosi, "awa fe Eko ni gedegbe"
Nwon fi ibanuje ola ṣawada.
Gedegbe; omo Eko ko si ninu awon alakoso iṣe Ijoba,
Gedegbe; eni-iwaju fekukaka r'ipo ehin;
Gedegbe; ile di wiwo mo wa lori,
Gedegbe; omo Eko d'eni a nle lo si Surulere;
Gedegbe; Oba Eko d'ajeji si Igbimo awon Oba,
Gedegbe; Ola at'ogo ijoye Eko fe d'ohun itan;
Gedegbe; Okere gori iroko oju ode da,
Abere bo lowo adete, oran d'ete
Ko ha tan bi, enyin abinu-ori fi fila de furo?
Hun! Rikiṣi pa awon alabosi, awo ya.
Kaka ki nwon s'oga, nwon wa ipo omo-ehin ti!
Nwon rope bi Eko ba wa ni gedegbe, agbara di tiwon,
Nwon di oluwa oba at'ijoye:
Nisisiyi, imoran won di asan.
Ipo ola ti nwon nwa pora mo won loju:
Nwon wa mo pe Eko ni oluwa, ki iṣe ilu agbelero,
Ipo ati ola Eko ga koja aṣe ohanran;
Ṣugbon awon bebije wonyi ko fe piwada,
Nwon ko fe mo pe Eko ki ise kekere ninu omo alade n'ile wa,
Eko gbodo wa, layekaye, pelu Ipinle Iwo-Orun.
Kini nwon nfe bikoṣe agbara lori omo Eko?
Kini nwon nlepa bikoṣe ire ti ara won nikan?
Bi omo Eko ba d'alarinkiri, nwon ko ko.
Enyin omo Eko, ṣe e ngboro mi?
Enyin le gbe ola Eko ta f'Egbe Alakuko,
Enyin le fi ote s'omo d'eru lairehinwo:
Ṣugbon biba lo ba, koi baje koja atunṣe,
E mura, e pimopo mu "wura" nyin kuro niwaju "elede".
A dupe, Edumare pese anfani,
A npete eto iṣelu titun fun ile wa.
Egbe Afenifere si ti mura tan lati gbe nyin nija.
E mu ikorira ati keta kuro lokan,
E pa ote wewewe ti sapakan:
E gbarajo, e fimoṣokan gba Eko sile lowo ikogun,
E pinnu lati wa pelu awon enia nyin ni Ipinle Iwo-Orun,
Bi e ba ko lati wa ipadabo Eko si ipo ola ibinibi,
Bi e ba fi "temi ṣa" so Eko d'ilu yepere,
E maṣe gbagbe, enyin yio je eso ajara,
Ehin awon omo nyin a si kan lehin ola.
Awon ara-isale ko si ni ṣaiberewo;
Mo gbo, awon kan tun fe ṣe "boju-boju",
Nwon tun fe fona eburu gun nyin loko lakotun,
Nwon fe ko ile titun fun "akuko" n'Isale-gangan;
Enyin omo Eko, e maṣe gbo tiwon,
Ire ti ara won li olukuluku won nwa pelu etan;
Mo wi fun nyin, e maṣe ṣe aiya nyin le,
E maṣe jeki Eko kuro ninu ajumoṣe Ipinle Iwo-Orun
Hausa ko fe ki Fulani daduro,
Ibo ko fe ki Ogoja ati Kalaba kuro lara on:
Ṣugbon ile re pa won po, nwon ko b'ara won tan,
Eṣe ti Eko yio fi kuro lodo ibatan re?
Eṣe ti Hausa ati Ibo yio fi ota sarin wa,
Ki aiye tiwon ba le dun ju?
Enyin omo Eko, enyin yio ha gba lati di alailara?
Enyin yio ha so ile nu lati ko apo iya?
E so fun won, ti Hausa ni ti Hausa,
Ti Ibo ni ti Ibo,
Ti Yoruba ni ti Yoruba,
Eko ko ni kuro ninu ajumose ile Oduduwa.

## Ẹ MAA KA IWE IROHIN YORUBA NIGBAGBOGBO






